# LILỌ KURO NI OKE SINAI

## Numeri 10:1-13, 29-36

## ẸKỌ 91 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Wá ba wa lọ, awa o ṣe ọ li ore" (Numeri 10:29).**

### A Fi Awọn Ọmọ Israẹli si Eto ni Oke Sinai

Fun ọdún kan ni ẹgbẹ́ nla awọn Ọmọ Israẹli ti pagọ yí Oke Sinai ká. Lati ori oke wá, laaarin àrá, iná ati eefin nla, Ọlọrun ti ba awọn Ọmọ Israẹli sọrọ O si ti fi Ofin Rẹ̀ fun wọn. Mose ti sunmọ tosi sọdọ Ọlọrun ninu awọsanma, o si ti gba Ofin Mẹwaa lara walaa okuta meji. Ninu iju Sinai a ti kọ́ Agọ gẹgẹ bi ilana ti Ọlọrun ti fun Mose ni ori oke, iná lati Ọrun si ti jó ẹbọ lori pẹpẹ, eyi ti o n fi hàn pe Ọlọrun ti tẹwọgba iṣẹ wọn. Ọlọrun ti fun Mose ni ọpọlọpọ aṣẹ, eyi ti o kọ́ awọn eniyan naa bi wọn ṣe le gbé pọ̀ ni alaafia ati ayọ̀, nigba ti wọn wa ni iju ati nigba ti wọn ba de Kenaani. Ọlọrun ti ṣeto awọn ajọ ati akoko ajọyọ ti wọn ni lati maa pamọ fun ọpọlọpọ ọdun ni ọjọ iwaju. Ohun gbogbo ni a fi seto, akoko si to nisisiyii fun awọn Ọmọ Israẹli lati bẹrẹ irin- ajo si Ilẹ Ileri.

### A Ṣamọna wọn nipa Ọwọ̀n Awọsanma

Ọwọ̀n awọsanma nigba ọsan ati ọwọ́n iná ni oru ni o ti n ṣamọna awọn Ọmọ Israẹli lati igba ti wọn ti fi Egipti silẹ. Nigba ti a pari kikọ́ Agọ, awọsanma naa ti sọkalẹ lati ori oke wá o si ti sinmi lori Ile Oluwa. O ti duro ni Sinai fun ọdun kan gbako nigba ti awọn Ọmọ Israẹli n reti aṣẹ lati tẹ̀ siwaju. Eyi ni yoo maa ṣe amọna wọn: nigba ti awọsanma ba duro, awọn Ọmọ Israẹli a pagọ; nigba ti o ba si ṣi ti o si lọ siwaju, wọn o tẹ̀ siwaju, i baa ṣe lọsan tabi loru. Nigba miiran wọn le pagọ fun ọjọ diẹ, nigba miiran oṣu kan, ati nigba miiran ọdun kan tabi ju bẹẹ lọ. Ṣugbọn niwọn igba ti awọsanma naa ba duro lori Agọ, wọn o duro.

Ọlọrun ti paṣẹ fun Mose lati ṣe ipè fadaka meji eyi ti alufaa yoo fun nigba ti wọn ba n fẹ ba awọn Ọmọ Israẹli sọrọ. Awọn ipe miiran jẹ ti awọn olori awọn ẹya lati pejọ sinu Agọ lati gba aṣẹ lẹnu Mose; awọn ipè miiran le jẹ fun ogun tabi lati tẹ̀ siwaju. Nigba ti itẹsiwaju ba bẹrẹ ẹya kọọkan le mọ̀ nipa ohun ipè naa igba ti o ba kàn wọn lati tẹ siwaju.

Ẹni kan ni lati maa ṣọ́ ẹṣọ, nigba ti awọn iyoku tilẹ n sùn paapaa, nitori ọwọn awọsanma le ṣí laaarin oru nigba miiran awọn Ọmọ Israẹli si ni lati tẹle e lẹsẹkẹsẹ. Awọsanma yii jẹ́ apẹẹrẹ ifẹ Ọlọrun, awọn eniyan naa si ni lati kọ́ mọ ifẹ Rẹ̀ ki wọn to le ṣe e. Lẹsẹ kan naa ti awọsanma naa ba ti ṣi, ipè ni lati dún lati ta awọn eniyan jí lati tẹ̀ siwaju.

A ni lati maa wà ni ipò iṣọra lati mọ ifẹ Ọlọrun ki a si feti si ọrọ awọn iranṣẹ Ọlọrun awọn ti n ṣọ́ ẹṣọ lori wa ti wọn si "nfun ipè" ki a ma ba bá wa nibi ti a ti n toogbe ki a si ṣaigbọran si Ọlọrun.

### Irin naa Bẹrẹ

A ṣeto awọn Ọmọ Israẹli a si ti fun wọn ni aṣẹ fun gbigbé wọn ni ilẹ Kenaani, akoko si ti tó fun wọn lati lọ si Ilẹ Ileri. O dabi ẹni pe ohun ti wọn n reti fẹrẹ tẹ̀ wọn lọwọ, nitori Kenaani jẹ́ irin ọjọ mọkanla pere si Oke Sinai.

Wo o bi wọn ti bẹrẹ irin-ajo wọn pẹlu ireti nla ninu ọkàn wọn! Aadọjọ ọkẹ eniyan (3,000,000) pẹlu ọ̀wọ́-ẹran wọn ati agbo ẹran wọn! Lai pẹ wọn o wà ni ilẹ kan ti o "nṣàn fun wàra ati fun oyin" Lai pẹ wọn o ni ile ti wọn nibi ti wọn o maa gbé ni itura ati lai si ewu. Wọn o gba ilẹ rere naa ti Ọlọrun ti ṣe ileri fun Abrahamu lati fun awọn ọmọ rẹ̀, ki wọn ma ba tun jẹ́ ẹrú mọ́. Gbogbo wọnyii ni Ọlọrun i ba fi fun wọn bi o ba ṣe pe wọn kò ṣe aigbọran si I.

Wo o bi itara lati sin Ọlọrun ti maa n pọ̀ to ni ibẹrẹ ninu ọkàn ẹni ti o ṣẹṣẹ ri igbala! Idaniloju nla kan maa n wà ninu ọkàn rẹ pe oun ni agbara lati bori ohun gbogbo, ati pe lai pẹ oun yoo bẹrẹ si jẹ igbadun awọn ibukun ti o pọ̀ pupọ ti Ọlọrun ti ṣeleri. Bi o ba gbẹkẹle Jesu sibẹ, idaniloju yii yoo wà ninu ọkàn rẹ̀. Ọlọrun a si maa ṣe ohun nla fun un. Ṣugbọn idanwo yoo dé; ni ọpọlọpọ igba awọn eniyan a si maa wo wahala wọn, wọn a mú oju wọn kuro lara Jesu, wọn a si rẹwẹsi pupọ. Ọna naa a wá ṣoro, wọn a si sọ itara ti wọn fi tẹle Oluwa ni ibẹrẹ nù Lai pẹ aarẹ yoo mu wọn ninu iṣẹ Rẹ̀, wọn a si gbagbe pe O ti ṣeleri lati ja ija wọn fun wọn. A gbọdọ kọ́gbọn nipa apẹẹrẹ ti a fi fun wa nipa awọn Ọmọ Israẹli. A le ri ibukun ti wọn padanu rẹ nipa ṣiṣe aigbọran si Ọlọrun, nitori naa a ni lati ṣọra lati ri i pe a wu U ninu ohun gbogbo ti a n ṣe. Nigba naa a o gbadun awọn ileri ti O ti ṣe fun awọn ọmọ Rẹ̀.

### Ẹya Kọọkan ni Ipò ti Rẹ̀

A ti fun ipè eyi ti o n sọ fun ẹya Juda lati bẹrẹ irin-ajo naa. Labẹ ọpagun ẹya Juda ni awọn ẹya Issakari ati Sebuluni n rin lọ, a si maa n kà wọ́n mọ́ ẹya Judah lai ṣẹṣẹ darukọ wọn lọtọ. Awọn wọnyii ni ẹ̀ya ti o maa n pagọ si ila-oorun Agọ, ni iwaju ẹnu-ọna rẹ̀.

Nigba ti o ba to akoko ti awọn ti o wà labẹ ọpagun awọn ọmọ Judah yoo fi ṣi tan, awọn ọmọ Gerṣoni ati awọn ọmọ Merari yoo ti tú Agọ naa palẹ̀, wọn a si ti mura tan lati tẹle awọn ti iwaju. Kẹkẹ mẹfa ti a bò, ọkọọkan eyi ti akọ maluu meji maa n fà, ni o maa n ru awọn ohun ti o wuwo ninu Agọ naa.

Nigba ti ipè ba dún lẹẹkan si i akoko tó fun awọn Ọmọ Israẹli ti o pagọ si iha guusu Agọ naa lati ṣi tẹle wọn. Awọn wọnyii ni awọn ti i maa rin lọ labẹ ọpagun Reubẹni, ninu wọn si ni Simeoni ati Gadi wà. Lẹyin eyi ni o kan awọn ọmọ Kohati, awọn ti o n ru ohun-elò inu Agọ lori ejika wọn. Ọlọrun ni awọn nnkan wọnyii jẹ́ mimọ́ pupọ ju eyi ti a le gbé le ori kẹkẹ lọ, ati pe awọn ọmọ Lefi ti a yàn fun itọju wọn ni lati fi tọwọtọwọ rù wọ́n.

Ipe ti yoo tún dún tẹle eyi yoo mu ki awọn ti ibudo ti o wà ni iwọ-oorun Agọ ki o bọ́ si ipò ti wọn ninu irin-ajo naa. Awọn ẹya Efraimu, Manasse ati Bẹnjamini a maa rin lọ labẹ ọpagun Efraimu. Ati lẹyin wọn labẹ ọpagun Dani, ni awọn ẹya Dani, Aṣeri ati Naftali wà, awọn adalu eniyan a si maa bọ̀ ni ẹyin wọn.

**"Wá Ba Wa Lọ"**

Ẹbi iyawo Mose n gbé nitosi Sinai nibi ti awọn Ọmọ Israẹli ti lo ọdún naa, nigba ti awọn ọmọ Ọlọrun si mura tan lati tẹ̀ siwaju, Mose beere lọwọ ana rẹ̀ bi yoo ba bá wọn lọ. Ọlọrun ti ṣeleri ọpọlọpọ ohun rere fun awọn eniyan Rẹ̀ eyi ti Mose n fẹ ki awọn olufẹ oun jẹ́ alabapin ninu rẹ̀. Ilẹ Kenaani jẹ ilẹ ti o dara pupọ ju aginju yii lọ lọnakọna, eyi ni yoo si di ilẹ-ini awọn Ọmọ Israẹli. Hobabu ki yoo ha kalọ lati gbadun ire ilẹ naa?

Awa ti a n sin Ọlọrun maa ngbadun awọn ibukun Rẹ̀, a si mọ̀ pe O tilẹ ni ohun ti o ju wọnyii lọ ti O pese silẹ fun awọn ti o fẹ Ẹ. A n fẹ lati maa sọ fun awọn ẹlomiran nipa ifẹ nla Ọlọrun ni ọna ti o jẹ pe awọn paapaa yoo fẹ lati sin In. Kò yé wa to bi ọpọlọpọ awọn eniyan ko ṣe yàn lati jọwọ ọna ẹ̀ṣẹ wọn silẹ, eyi ti o n fa ọpọlọpọ wahala ba wọn, ki wọn ba le ni ayọ̀ ti o jẹ ti kiki awọn ọmọ Ọlọrun nikan. Wo o bi inu wa ti n dun to nigba ti ẹni kan ba pinnu lati dara pọ̀ mọ́ wa lati jẹ alabapin igbadun ati ibukun ti Jesu n fun wa nisisiyii ni oju ọna wa si Ilẹ Ileri naa, ki o si jẹ alabapin pẹlu wa ninu ogún awọn ohun ti Ọrun nigba ti Oluwa ba pada wa lati wa mu awọn ti Rẹ̀ lọ.

**AWỌN IBEERE**

1. .Bawo ni o ti pẹ tò ti awọn Ọmọ Israẹli fi wà ni Oke Sinai?
2. Darukọ diẹ ninu awọn ohun ti o ti ṣẹlẹ nibẹ.
3. Bawo ni awọn Ọmọ Israẹli ṣe n mọ̀ pe akoko to lati tẹ̀ siwaju?
4. Nibo ni awọn Ọmọ Israẹli n lọ, bawo ni o si ti jinna to?
5. Ki ni Mose sọ fun ana rẹ̀?